# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

VOL. II. No. 56. SATURDAY, AUGUST 4, 1923. FOURPENCE.

Mundlos on top Mundlos.

### A. KESSLER,

GERMAN HAMBURG.

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos,*" "*Adler*" ati Ẹrọ-riran bata ni 7, Labinjọ Lane.

9 AUG 1923








A ranṣẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*
A si nta Chun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere, Waji.
E le ri ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati H. Campos, ti Campbell Street.

Mundlos on top Mundlos.

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

### J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laika, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.







Awọn Oyinbo Onisowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun sikole fun tita ni owo ọpọ̀kan-ọyọ̀kan.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-erọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## **Lagos Ekitiparapo Society.**

*Patron*: HIS HIGHNESS

THE OWA OF ILESHA.

The Council of the above Society respectfully request all Ekiti and Ijesha Children (Male and Female) who at present are not members of the above Society to register their names personally or by letter at the Office of the Society,

**Arapa Hall,**

Williams Street, The Secretary will be in attendance from 8 to 12 noon and 2 to 5 p.m. until 31st of August, 1923.

OGUNTOLA SAPARA,
*President.*

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN I

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MAṢINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onisọwọ-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to sẹsẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māṣe leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

E lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

### Ẹ KU ANA, AIKINI IJẸTA!!!

Awọn Ẹgbẹ Idapọ (*The People's Union*) ṣe Ipade kan ni Ile Afari Ogun ni *Saturday* ọsẹ to kọja fun iyan enia sinu Ajọ Igbimọ Aṣofin Nigeria. Dr. John Randle baba Ẹgbẹ na ni alakoso Ipade na. Dr. Ọbasa lo fi alakoso na han Ipade; ẹniti o rohin iṣẹ ti o ni awọn Ẹgbẹ on ti nṣe lati ọdun jọjọ sẹhin ati owo ti o ni nwọn ti na, o dun ni pe Alakoso na sọrọ ti ko yẹ ẹ bi agbalagba lati sọ nipa bibu mọ to bu mọ Ọgbẹni Thomas H. Jackson *Editor* iwe Irohin ọsọsẹ ti a npe ni "*Lagos Weekly Record*" pe *Editor* na kọ iwe ọtẹ sinu iwe rẹ na ti ọjọ kẹsan oṣu *June* to kọja, nigbati Ọgbẹni *Editor* yi ko si ninu Ipade wọn na lati da a lohun nibẹ lẹsẹkanna: diẹ ninu awọn ero Ẹgbẹ to sọrọ ni eyi Alufa Sunmọnu Akangba, Yesufu Agoro Olori awọn Giwa Giwa, Sanni Adewale, ati J. A. Oṣodi. Dr. Akinwade Savage sọrọ, o si jẹ ohun ẹdun ẹni pe ọrọ rẹ yi bi puro awọn to wa si ipade na ninu, tobẹ ti rudurudu fi wọ ọ fun igba diẹ;ṣugbọn Alakoso bẹ awọn enia ki nwọn mu suru. Ọgbẹni J. A. Oṣodi Ọmọ oru-ndu Arulogun bi efin sọ kasinkan ọrọ ti gbogbo rẹ jẹ otọ tobẹ ti a fi ṣapẹ fun u lati yin i, fun igboiya rẹ ti ko fi ọrọ b'ọpo b'oyọ. Alakoso pe awọn ti nwọn wa si ipade lati sọrọ si ohun ti awọn Ẹgbẹ na pe wọn si. Ọgbẹni A. Laotan fa ilu ya nipa ọrọ otọ to fi gun ẹnikẹni ninu Ipade na lara, o sọ pe ẹnu ya on pe awọn to pe ilu wa si Ipade wọn si nsọrọ ebu si Ẹgbẹ miran lara; l'aiṣẹ-l'airo o si sọ pe kò yẹ ki irufẹ iwa abinuku yi ma wa larin awọn agbalagba wá, pe o yẹ ki nwọn "mọ agba-l'ẹgbọn" eyini nipe ti Ọlọrun ba fi awọn kan ṣe aṣaju nkan, o yẹ ki a pa'rapọ lati mọ eyi, papa ni irufẹ nkan to de'lẹ yi. *Editor* Eko Akete fesi si ọrọ ti ọkan ninu awọn isangbe Alaga sọ ti o wipe Ẹgbẹ wọn jẹ Ẹgbẹ ti Ọba ati ti Ijoye, ati pe bi Ẹgbẹ kan ko ba jẹ bayi, awọn ko jẹ ba Ẹgbẹ na ṣe pọ, Ọgbẹni *Editor* na si dide lati bere Ọba ati Ijoye melo lo wa larin wọn ninu Ipade ọjọ na. Ọgbẹni *Editor* na si tun bere pe ninu owo ti nwọn sọ pe nwọn na yi elo ni eyiti nwọnyi fi sapakan fun Apo-owo-ṣiṣe iranti *Bishop* Johnson eyiti awọn agbagba kan ninu ẹniti alaga ọjọ na Dr. John Randle nṣe akapo rẹ, ṣe Ipade kan ni vara kan ni Gbangan Ile Afari Ogun ni ọjọ 27 *June* 1917, ṣugbọn ti a ko ri kọrọ tabi abọ aba na titi di oni! ko si esi fun ọro yi bakanna.

Ọgbẹni James Alẹṣinlọyẹ Williams sọrọ o si powe kan ti a gbọ pe o mulẹ gidigidi Ọgbẹni E. Olu: Bright sọrọ pẹlu ati awọn jakanjakan awọn Ọgbẹni David Taylor ati Wahabi Shitta pẹlu awọn isangbe alakoso na ninu ipade yi.

Ipade tuka niwọn agogo meje-abọ alẹ.

### LẸLẸ LO NFẸ IYAWO DI TABA!

A o gbe omidan Adelaide Idowu ọmọ Ọgbẹni William A. Cole ti 11, Ita-Apọngbọn ni'yawo ni agogo mẹwa abọ aiọ ni *Church Wesley*, Olowogbowo, ni *Thursday* ọsẹ to mbọ fun Ọgbẹni William A. King. Ki Baba jẹ ar'adun nibẹ. Aṣẹ

### O YẸ Ẹ O, ALARA-GBAYIDA, A YỌ L'ẸGBẸ DARADARA.

Ọgbẹni J T Akinrẹmi White *Agent* awọn Oyinbo Onisowo ti ilu oyinbo Overmann & Co., ẹniti a sọ pe o di ọdun-

mọkan-le-logun nibi iṣẹ rẹ ninu iwe yi ni ọsẹ diẹ sẹhin, yio ṣe Idupẹ Pataki ni *Church* rẹ U.N.A. Jehovah Shalom ninu Isin Mimọ arọ ọla a si gbọ pe, yio pe awọn ọrẹ ati ojulumọ ti o wa ba ṣe ẹyẹ Idupẹ yi l'enia lẹhin isin na. Bẹ ni tirẹ ri, Anawo bi ẹlẹda ! ! !

GBERE RẸ, ỌMỌ OLOWU ODURU ỌMỌ IBI TI ẸMỌSỌ PỌ JU OMIDAN LỌ ! ! !

Ni ọsẹ to kọja a sọ pe Ọgbẹni Francisco Elias Silva (Baba Yetunde) ọmọ onile kiniun ni Ita Ọbadina fi iṣẹ silẹ ni oṣu to kọja a wa ri idi rẹ dajudaju pe ko fi iṣẹ silẹ ṣugbọn "gba were, nko gba were, ni ọja fi ntu," tabi ede-ai-ye-ede lo wa larin on pẹlu ọga ibi iṣẹ rẹ na, ati pe nwọn ti ṣe atunṣe ọrọ na, o tun nṣe iṣẹ rẹ lọ eyi to jẹ Olori awọn Akọwe ile iṣẹ na bi ti atẹhinwa.

Ọgbẹni yi Francisco Elias Silva ni *Agent* akọkọ ni inu iṣẹ S. Thomas & Co., ni ọdun 1913.

IYA NI WURA.

A ba Ọgbẹni Kitoyi Ajasa *Lawyer* ati *Editor Nigeria Pioneer* ati awọn Iyekan rẹ kẹdun iku Iya wọn Mammy Macauley to ṣẹlẹ ni *Monday* ọsẹ yi.

Ki Baba gbe e s'afẹfẹ rere.

IPADE GBOGBO-GBO TI NIGERA.

*Nigeria National Democratic Party.*

A o ṣe Ipade nla ti Ẹgbẹ yi ni Ile Afari Ogun ni, agogo mẹrin ọjọrọ *Saturday* t'o mbọ.

## IBAJẸ AWA IMALE KUN APẸRẸ AJADI.

*(Lati ọwọ Ajilaran.)*

Ojẹ ẹdun nla fun awa ọdọmọde Imale loni lati ripe ọpọlọpọ ipo ni awa imale Eko ti sọnu nipa ọrọ ẹtan ti pupọ ninu awọn Alufa oniwasu wa ti sọfun awọn baba wa, pe kotọ ki a ran awọn ọmọ wa lọ si Ile Iwe; ti awọn baba na sin gba si bẹ gegẹ. Eyiyi mu ki abamọ nlanla ba awa Imale loni. Bi ọbajẹpe awọn baba wọnyi wa ni aiye ti awọn oniwasu wọn na sin wa ni aiye pelu, ti wọn sin ri bi nkan ti nlọ si ni aiye loni awọn mejeji wọn ko ba tutọ si arawọn loju. Ero ọkan wọn ni pe gbogbo awọn enia to ba mọ iwe yio wọ inu ina, nigbati ọrọ na ko jẹ bẹ rara. Bojẹpe wọn fun wọn ni aye lati kọ iwe ni, ọpọlọpọ ọmọ Imale ni ko ba di onipo giga loni ninu Iṣẹ Ọba, pupọ ninu wọn ni ko ba di *Lawyer* tabi *Doctor*, ṣugbọn nipa iwasu bai, wọn jẹ ki ọmọ wọn padanu ipo wọn yi. Awọn ọmọya wa to jẹ onigbagbọ lo tete gbọn, wọn si fi ẹsẹ ọmọ wọn le oju ọna na, gbogbo ọmọ wọn di onipo giga ninu iwe, omiran di *Doctor* tabi *Lawyer*, *Printer* etc., loni yi pupọ ninu awọn oniwasu ti wọn ti kilọ fun awọn enia wọn ati awọn na papa pelu di ẹniti onpakubẹkubẹ lọdọ awọn *Lawyer* ati awọn *Doctor* nigbati ojẹpe owo ti awọn onigbagbọ fi kọ ọmọ wọn ni Iwe ti wọn fi di *Lawyer*, koju eyiti Imale fira lawani, ẹṣin on kẹkẹ lọ. Ṣugbọn loni odun awa imale tani oye lori ju oju egbo lọ, asẹhin wa asẹhin bọ, awa Imale di *cocoa* ti awọn *Lawyer* nka jẹ. Bi imale ti pọ to ni Eko loni ti owo sin yayẹyẹ si wọn lọwọ, oto ki wọn ni *Lawyer* bi adọta ki *Doctor* to ọgbọn tabi ju bẹlọ, nitori gbogbo *Church* to wa ni Eko ko ju 22 lọ, ṣugbọn Mọshalashi Imale jẹ 46, lori gbogbo wọnyi, a ko ri ikan ninu awọn ọmọ Imale ti baba rẹ jẹ olowo ko lọ kọ *Lawyer* tabi *Doctor*. O dabi, bi awa Imale ti pọto bẹni ibajẹ wa pọto.

Pupọ ninu awa Imale lo sin jẹ olowo nlanla, kaka ki ama bu ọla fun olowo ki a sin ma fi ọna to le fi owo na tun Ilu wa ṣe han, ṣiṣe ni awa yio tọka rẹ fun awọn ọmọ wẹwẹ ki wọn ma kọrin bu kakiri Ilu, nigbati Oluwa ba sin ran olowo yi lowọ, ti ọwọ rẹ ba tẹ ọkan ninu wọn nipasẹ ṣiṣe aṣiṣe kekere kan, wọn asin fina mọ, wọn a fi alaṣiṣe na si ẹwọn, lọna bai, orukọ rẹ yio bajẹ. Boya ko ba jẹ enia kan ti aleyan si Igbimọ lọla, a fi ẹkẹ ebu ba ara rẹ jẹ.

Ninu otiṣi isin mẹta to wa ni Eko, Aboriṣa, Igbagbọ ati Imale: Imale lo fẹran lati ma kọrin bu enia kiri Ilu ju, awọn oniwasu wọn a sin ma fi wasu powe si ẹgbẹ wọn to jẹ Imale pẹlu. Bi o ba fẹ ri ẹlẹya awa Imale, bi oku kan ba ku ko lọ sibẹ, ko lọ gbọ iwasu wọn, kakaki wọn tun ẹniti ọfọṣẹ ninu ṣe ki wọn sin gbadura ki wọn tuka, t wọn ba fi oju kan ọta wọn nibi oku na, wọn a fi ẹtẹ silẹ wọn a ma pa lapalapa, ibajẹ, ni yi.

*Koi li pari.*

---

TO MR. D. A. LASOJU OF LAGOS.

If Mr. D. A. Laṣoju late of Kano will call at our Office during business hours, he will hear something to his advantage

## Letters to "Eko Akete."

Sir,

Permit me to correct an error which occurred in your issue of the 21st July.

In an article written in Yoruba, a remark was made that Calabar women have been the cause of venereal diseases now rife in the colony. To say the least, it is the most unprovoked attack to have associated the name of Calabar with the women concerned.

However, I shall not be hard on the writer, as his article has prompted the performance of a duty long since deferred.

As time and space will not permit a minute history of the Calabar people, I shall indulge only in a very brief description of tribe.

The people of Duke Town, Creek Town, Henshaw Town, Old Town, Ikoneto, Ikohofiong and Adiabo compose the tribe known as Efiki tribe.

No people outside these towns have any right to claim Calabar as their native land.

We all know that for political convenience the great country of Nigeria is divided into the Western Province, with Lagos as the chief town; the central province with Warri as the head; and the Eastern province with Calabar as the principal town.

A glance through the map of Nigeria will show that they are more than thirty towns forming the Eastern province. Among these are Akunakuna and Atam, the native land of the women in William and Porto Novo Streets.

There are many Yoruba people here who could testify that the Atams are no more Calabar people than I am a West Indian.

Calabar women are not above a dozen in Lagos, and these have no marks to distinguish them from other West African tribes.

The Atams have their tribal marks, and a district language in which I do not understand a syllable.

Many of them here have never seen the land of Calabar since their birth.

It being their darling wish to be passed as Calabar women, they spare no pain in learning our language as soon as they arrive in the Colony.

It is rank folly that among themselves, and in the presence of a Calabar person they behave as Akunakuna people, but before their customers every effort is made to drown their nationality.

Attempts have been made, with some success, to oust them from Calabar.

The people at home will recoil with horror and indignation to hear that the people they are turning out of their land are classed here as their very sisters.

If their being under Calabar for political purpose entitle them to the name, then all in Nigeria are Lagosians.

It is true that the ancient town of Calabar is now humiliated, but the people will not thank any one who aims at wounding their national pride.

Hoping that my feeble efforts will serve as a useful guide for future references, and thanking you for space allowed.

I reamain,

Sir,

Yours sincerely,

ASUQUO E. DAVIES.

[ If, as our correspondent states indirectly, Calabar women are as immaculate as the snow in this unsavory business, can they cast the proverbial first stone? From the information at our disposal, we are afraid our correspondent is straining at a gnat and swallowing a camel. ]

ED. "Eko Akete"

**Mr. B. O. Joseph.**

of 64, Breadfruit Street, Lagos, begs to inform the Public that he is now a free Commission Agent, and he is now prepared to sell any kind of goods on behalf of any firm.

*21 years' experience in trade.*

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

*Business Place* :—
20, Balogun & Breadfruit Streets, Lagos.

FORTH COMING MARRIAGE.

A marriage has been arranged and will take place between Miss Adelaide Idowu Cole, daughter of Mr. William A. Cole of Apongbon, St., Lagos, to Mr. William Adebambo King, son of Mr. Charles Adeyemi King of Ereko, Lagos, on the 9th instant in Wesley Church, Olowogbowo, at 10.30 a.m. *No Cards.*

# EKO AKETE.

Eko, Saturday, August 4, 1923.

## O ṢE, ARAKUNRIN MI!!!
(ALAS! MY BROTHER.)

Cudugbẹ t'o ja ni ilu *America* ni lọlọyi nipa ti ijangbun t'o ba Marcus Garvey ti a ba rojọ pe o jẹ owo awọn t'o fowo sinu Ẹgbẹ ọkọ Enia dudu (*Black Star Line*) ti a si fi s'ẹwọn ọdun marun jẹ irohin agbọ-da-gba-nu nigbati a kọkọ ri "Labari" na ka ninu Iwe-Irohin Oyinbo ti a npe ni *Reynold's Newspaper* ti a ri gba l'ọsẹ diẹ sẹhin.

A ri diẹ ninu Iwe-Irohin ọsọsẹ ti a ntẹ Ilẹ yi, t awọn fi ọrọ na ṣe "ja-ginni, dun mọ mi!!!" irufẹ Iwe-Irohin bẹ gbagbe pe ayida-aiye le ba awọn na bakanna l'ọna yi; kaka ki a ca o ẹniti a gbọ pe pakute aiye mu yi, nṣe ni awọn ẹlomiran nyọ si iru iṣubu enia bẹ, bi ẹnipe awọn papa bọ lọwọ idamu aiye.

Nitotọ awa papa ko fẹ purọ ninu ọrọ isọkusọ ti ẹni na Marcus Garvey ma nsaba ni *Liberty Hall*, gẹgẹ bi a ti nri i ka ninu Iwe-Irohin *Negro World* ti o jẹ ti Ẹgbẹ t'o da silẹ.

L'oju wa Garvey f'ẹtẹ silẹ o npa lapalapa; kaka ki o san ṣokoto rẹ giri, ki o si mu iṣẹ i'ubọ lọsiwaju Enia dudu ṣe, nitori o jẹ nkan pataki ti o fi da Ẹgbẹ bogbo-gbo ti Enia dudu na (*Universal Negro Improvement Association*) silẹ ni *America* ni ọdun 1917, o bẹrẹ si gbe tasi ọrọ-ija lu awọn Agbara aiye, bẹni Ilu Oyinbo na ni ẹlẹgbẹ awọn t'o ngbe ija ko bayi wa, bi o ti wu k' o ri enia ni enia nje nibi gbogbo, o da ni loju pe, pupọ ninu awọn mbo *America* ni ki yio fẹ iwa a-foju-ka-ti Garvey nhu yi; be si ni awọn Iyekan to wa nibẹ nẹlu ki yio ni inu didun si iwa Mo Mọ-tan bẹ. eyi yio si mu ki ja ṣọ lọwọ ṣọ-lẹsẹ.

yẹ ki Garvey mọ pe a ki i gbe inu 'kọ, ki o si lo ọgbọn ẹlẹ; alaiṣe eyi idanwo nla yi ba a.

A ranti ni ijọ wọnni ti Ẹka Ẹgbẹ na ti a da silẹ nibi ti a si nṣe ipade rẹ ni alalẹ *Saturday* ni Ile Iwe St. Peter, ti ndun yungba ti orin npe orin ranṣẹ, ọrọ iṣiri si lọ ja-nrẹrẹ, ti'le kun tobẹ ti ko si ẹniti ko fẹ ṣai wọ inu Ẹgbẹ na; ṣugbọn ni akoko yi, ẹru ba wa gidigidi pe, didun yungba bayi, lẹ mu ki Ẹgbẹ na fọ lairo-tẹlẹ, o si dabi ẹnipe ọrọ wa ṣẹ lẹhin bi ọdun kan ti a ti nṣe Ipade Ẹgbẹ na.

Bẹ l'ori, ẹniti o ma ṣe Aṣaju lati fi ọna to ni han awọn enia rẹ ni lati fi ori gba, "Iṣasun to ba ma jẹ ata, idi rẹ a pọn rodorodo;" bi a ti ba a l'aiye niyẹn.

Ẹnyin ọmọwe yio mọ otọ yi ninu Itan Igbesi aiye Jesu ni Jerusalem, ti Mọmọdu ni Arabia, ti Mazzini ati Garibaldi ni Italy, ati ti John Hampden ni England.

Marcus Garvey, o di sa kan, ki ẹkọ ti iwọ yio ri kọ ninu ile isẹmọ rẹ fun ọdun marun yi ṣe ọ ni rere, tobẹ ti a ba tun fi fun ọ laye ati fun ma ba iṣe rẹ lọ, Iwọ yio mọ bi a ti njuba awọn Alagbara ati bi a ti fi lakaye ṣẹgun iṣoro. O di gbere!!!

Ẹniti o d'ọgba Ẹwọn

B'o ri Garvey a bu s'ẹkun!!!

---

## ṢẸGAN-ṢẸGAN IBA JADE KO NI LARI.

Awọn baba wa a ma pa owe pe "Ẹniti o ri ejika gbe ẹwu, ki nri owo lati fi ra a;"-to-to o. Eyi ni ọrọ ẹniti o sọ ọrọ ẹgan si Iwe-irohin EKO AKETE, nipa iṣẹ nlanla *Cinema*, eyiti Olokiki Sakajojo da silẹ ni Idunmagbo, Isalẹ-Eko. Ohun ti o tọ si *Ọmọ Eko* ti o sọ ọrọ yi, nigbati o fi ibẹ silẹ ni ọjọ aisun ọdun Imale, iba sure lọ so'i Kereni Oyingbo boya oju rẹ le la bi Sakajojo, tabi on rẹ le jẹ ẹgbẹ, ati pe o si ti na irufẹ owo iyebiye ti Sakajojo na si *Cinema* yi latari asan, ohun pataki ti o jẹ ọrẹ rẹ ni nkan miran, eyiti o jẹ irọri fun u ni alalẹ.

O da mi loju pe lati igba ogun nami-nnalẹ, ti o ti fi Iwe-iwe silẹ, lati gbe orukọ ọmọ Eko ru, ti o jẹ iwọ ni "Eko l'a bi mi, ko ri fila de, ti awọn ilabiru ti o ba ni Ilẹ yi nra ẹṣin" o ko mọ daju pe nipa ilu Gọngọṣn edi-da-rẹ, ti iwọ njo kakiri, ko le jẹ ki o mọ pe o ti gbe Ọgba *Cinema* tirẹ mi, ti-ṣo-ti-ṣo, ti-panu-ti-panu, ti-ere-ti-ere, ti-tikiti-ti-tikiti ti iwọ àpa yi nsọrọ rẹ.

O ko le ṣai ma pẹgan ọdọmọkunrin ti o gbiyanju, ti ki nṣe amu-mi-mu-rawe bi iwọ ti o ti wọ Okun, wọ Ọsa; ti gbogbo rẹ di iwọ le lori, Sakajojo ko ni gbọngbọn lati duro ṣinṣin si idi Tikiti, nigbati ki nṣe were. Mo ro pe o ti ṣako lọ ni igbati Ologbe Jones ati awọn Oyinbo jakan-jakan miran nṣe *Cinema* l'Eko, Omi ko sa jẹ ki o ṣe akiyesi pe Jones papa lo nwa ni idi Tikiti Ọnu-ọna Ile-ẹgbẹ Afari-ogun (*Glover Memorial Hall*) ti o si ma ngba owo titi di igbati ere ba fẹ bẹrẹ, ki o to fi ibẹ silẹ. Iwọ ọmọ At'ọhun-rinwa, ti njẹ ọmọ Eko, ki Falana rẹ lọ ran ti ara rẹ o; ki o si wa mura lati fi *Notice* ere rẹ s'ode, ki o si ma duro ta Tikiti, "Ọmọ Ara-mu-kandu."

Sakajojo, gbogbo sanmari Eko titi kan ọmọ Isalẹ-Eko ati Idunmagbo nsala rẹ o, *Cinema* rẹ gbamuṣe; ma f'eti si ti "Ile-eiyẹ dara, ajule-ẹiyẹ sunwọn, kini ṣe ti ẹiyẹ ko re 'le" ti npe ara rẹ ni ọmọ Eko.

Emi ọmọ ALAROGBO.

## ẸBUN ỌMỌ

*Lati Ọwọ* J. M. A.

I.

Ẹbun ọmọ jẹ ohun ti olukuluku ẹda nnoga si lati iṣẹdalẹ aiye. O jẹ ipari gbogbo ẹbun ti o wa laiye yi, pe lẹhin ẹbun yi ko tun si eyiti o tobi jù u lọ mọ, tabi ti o niyi tobẹ mọ. Ọmọ, ibẹ lo mọ, ipari ẹbun. Awọn orilẹ ede miran ro pe awa enia dudu fẹran ọmọ pupọ, pe bi a ko ba bimọ, a ma dun wa. Eyi kiṣe aniyan awa enia dudu nikan rara. Ifẹ lati bimọ jẹ itẹle aṣẹ Ọlọrun, Ẹniti O sọ pe ki a ma bi si i, ki a ma rẹ, O tilẹ tun wipe ki a ma gba yin l'ori ilẹ (ṣugbọn ko sọ pe ki a ma bi ibi aiwọ bi ẹranko) lati inu Majẹmu lailai, aniyan lati bimọ jẹ ero ti o ga julọ ninu awọn ara igbani, titi fi de inu Majẹmu Titun. Ọran ẹdun Abraham ni pe ki on le bimọ bayi, Rachel tilẹ ja tirẹ ni ija aja-han gbangba, a ko ri ẹbun ti a le bun obinrin ara Ṣunẹmu, nitoripe o ri jẹ. o rọ ọ lọrun, ṣugbọn nitoripe ko bimọ, a bun l'ọmọ. Hannah, aya Elkanah ba Ọlọrun jijakadi pẹlu aisimi ninu adura, Ọba na si rẹ ẹ l'ẹkun rẹ. Sakaria, ninu adura aisimi, o tọrọ ọmọ, adura rẹ si gba. Apẹrẹ wọnyi to lati fihan pe ifẹ lati ni ọmọ ki iṣe arun ara awọn enia dudu nikan, bẹ kaiye ni a le pe e.

Eyiti o pamọ fun awa ẹda nigba miran ni pe, a ki ranti rara pe Ẹbun ni ọmọ jẹ, ẹbun ni owo, ọgbọn, bibini rere, ẹwa, ati awọn ẹbun yoku, ẹniti tabi ẹlomiran ti a ba si kọjusi ṣe lore lati ni owo ati ọmọ, tabi ọmọ ati ọgbọn, awọn bẹ a ma ṣiro pe ọgbọn inu wọn ni, mimọṣe wọn ni, iṣina nla ni eyi.

Ṣaṣa agbo ile ni a gbe nri ti owo ati ọmọ jọ npapọ, ko ṣe pe ko wa, ṣugbọn ko pọ rara ni. awọn ti a ba si ṣore nla bayi fun a ma foju tinrin awọn ti ko ri bi awọn ti ri. O ma buru o! Owo ko to fi ṣe igberaga si enia, nitoripe o le gunyẹ lọla a si fo lọ. Ọmọ ko to fi ṣe labilabijori, nitoripe ọpọ ọmọ ti a ro pe nwọn bọ lọwọ iku, a si fo ṣanlẹ, nwọn a ku, agbọsọgbanu ni iku wọn i si jẹ fun gbogbo enia. Nitorina o lowo ni o, o bimọ ni, o ni ẹwa tabi ọgbọn, maṣe fi ṣe igberaga tabi fọrifọri, ki Eṣu ma ba fi ọ sun Olodumare.

1. *Eṣe ti ọpọlọpọ enia ki bimọ?* Ibere na le pupọ, a fẹrẹ ma mọ bi a ti dahun rẹ pẹlu. Lọna kini, aibimọ awọn ẹlomiran le jẹ pe Ọlọrun ni ko fun wọn, boya rara, tabi ko tete fun wọn.

Ṣe o pẹ Abraham bẹ? bẹ na li o pẹ Sakaria, Ọlọrun ṣa se inu Rakeli fun sa kan, ko ṣẹhin Ọlọrun ṣà. Lọna keji, boya o le jẹ pe arun pataki kan ndi ọkọ tabi aya lọwọ, a ki mọ o le jẹ aiso gbe jẹ m'ọwọ ọkan tabi ekeji, nwọn a ti ipa bẹ ṣẹ ebu ti ko wọ. Lọna kẹta, bi Ọlọrun ba ri pe ko ni ṣanfani fun wọn ki pin fun wọn. Ki Edumare ma jẹki a bi ọmọkọmọ; idi rẹ ti awọn miran fi nkọrin pe "pengele, emi ki mo bi were."

[ *Koi ti pari* ]

**Wanted to Purchase.**

Handel's "Halleluiah Chorus" and "Coronation Anthem" in Gramophone Records.

***Reply to The Editor.***

## IGBẸ L' OWO WÀ.

**LAGOS—Ekuro.**

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£11 10—£12 fun *ton* kan

Epo.

£21 10—£23 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

Cocoa.

£23 10—£26 fun *ton* kan bakanna.
(according to quality)

**KANO—Competitive Prices**

Ground Nut—
Skins 1/10½ per lb, Hides 4d per lb

## POSI T'O JIRE.

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si:—

Ọgbẹni Hudson Cole,
P.O. Box 477,
Eko.


## MR. A. KESSLER,

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

## Pilsener Beer! Pilsener Beer!!

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"Lion Brewery Brand"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*

Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mẹjilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan. Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rẹ tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja şọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi:—

Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Ig: Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru ẹyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o jẹ onidẹ ( Brass )

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu ***Motor Transport.***

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30

7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9 30 a.m.

EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. | St. Peter's (Aiapako) | Rev. J. A. Cole |
| 3.30 p.m. | do. Harvest | „ A. B. Akiẹle |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 3.30 p.m. | do. Harvest | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10 30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | „ D. A. Babatunmi |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | „ S. A. Pearse |
| 7 p.m. | | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearse |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. T. A. White |
| 9 a.m. | Erelu | „ J. A. Lalẹyẹ |
| 7 p.m. | do. | „ M. I. O. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. H. Atundaolu |
| 6 30 p.m. | | „ E. A. Akinọla |
| 9 a.m. | Zion | „ N. J. D. Shomuji |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. I. O. Oyekunle |
| 4.30 p.m. | | Bro. L. A. Randle |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. R. O. Macaulay |
| 4 30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Paddicombe |
| 5 p.m. | | Bro. E. A. Ojo |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | do. |

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi — Bro. S. A. Coleman-Daniel

7 p.m. — Prof: Adeoye Deniga

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. — Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

**CHURCH OF GOD**

22 Ọdunlami Street, Breaking Bread Open Air Service—Edwin Matthew & Wm. C. T. Terrell

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D., ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sã kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ oluko awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## IWE-ITAN T'O KẸ RIRI

Ọrẹ,

Lọ ra Iwe Itan ti Ibadan ati ti Ọyọ ni Ile-itawe ti *C.M.S.* nibi, ṣile meji meji ati sisisisi ni a nta ọkọkan.

Ọgbẹni Isaac Akiyẹle l'o ṣe Iwe Itan ti Ibadan Ẹ o si ri ọwọ rẹ ninu ti Ọyọ pẹlu.

## BOOKS! BOOKS!! BOOKS!!!

"History of Ibadan" and "History of Ọyọ" by ISAAC AKIYẸLE are on Sale at the C.M.S. Bookshop, Lagos. 2/- 6d. each.

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

## JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged, Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*

c/o Aafani Motors

The Marina Lagos.

### ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo, ati Awọ Hausa ni oriṣiriṣi awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, ofẽfe, ati oriṣi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ,
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams.*—Alawọbata, EKO.


### NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

### AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo oja na ka.


## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagcs, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

MR. E. ADE: OGUNMOKUN,
*GENERAL TAILOR.*
47, Princes Street; Recently Established
*Try me and see.*

---

### WO'BI.

Ile òwò ti awọn Ajọsẹ ti a npe ni Ṣabu Ireti nbẹ ti 24 Ita Agarawu nibiti a gbe le ri oriṣiriṣi ṣ'ẹrẹkẹ ṣin ati ọti-amu-'nudun ra, si tun ni Ẹka Ṣabu kan ni 10 Ita Dosunmu nibiti ẹnikẹni le lọ ra ọja tirẹ ni ọpọku ọyọku.

Ọrẹ, kọwe si :—

Ọgbẹni SOLO. S. AJOSE,
*Alabojuto.*
ni 10, Dosunmu Street,
EKO.

---

### ENYIN ONIṢOWO EKO.

Ẹ wa polowo Ọja nyin sinu *Eko Akete*, kolẹgbẹ ni ede Yoruba inu rẹ, o jare, o si "Ka-yin, wọbọ-wọbọ."

Ẹ tete sure wa, "Awure" nduro de nyin !!! Owo pọ ọ ni yio na ọ, ẹnikeji.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.